# OMI LATI INU APATA; IṢẸGUN LORI AMALEKI

## Ẹksodu 17:1-16

## ẸKỌ 59 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ti gbogbo wọn si mu ohun mimu ẹmí kanna; nitori pe nwọn nmu ninu Apata ẹmí ti ntọ̀ nwọn lẹhin: Kristi si li Apata na"(I Kọrinti 10:4).**

**I A Ba Awọn Ọmọ Israẹli Wi**

1 Titẹ siwaju ninu irin ajo awọn ọmọ Israẹli mu wọn de Refidimu, lẹba Oke Sina, Ẹksodu 17:1
2 Aisi omi fun wọn lati mu mú ki wọn kùn si Mose, Ẹksodu 17:1-3; 15:24
3 Niwọn bi o ti jẹ pe Ọlọrun ni O ṣeleri lati bukun fun won, Mose ran awọn ọmọ Israẹli leti pe Ọlọrun ni wọn n kùn si, Ẹksodu 17:2; 16:8; I Kọrinti 10:13; I Awọn Ọba 8:56
4 Mose gbadura fun iranwọ ati imọran, Ẹksodu 17:4; 15:25
5 Ọlọrun paṣẹ fun Mose lati fi ọpa lu apata naa niwaju awọn agbaagba Israẹli, Ẹksodu 17:5, 6; 15:25; Orin Dafidi 62:1-8; 78:15-20; 105:41; Deuteronomi 32:3, 4, 18, 30, 31; I Samuẹli 2:2; I Kọrinti 10:1-4; Johannu 7:37
6 Mose sọ ibẹ naa ni Massa, ati Meriba (Idanwo ati Asọ̀), lati rán awọn ọmọ Israẹli leti ikuna wọn, Ẹksodu 17:7

**II Ogun pẹlu awọn Amaleki**

1. Awọn ara Amaleki fi ọgbọn arékerèkè gbogun ẹhin ti Israẹli, Ẹksodu 17:8; Deuteronomi 25:17, 18; Numeri 24:20
2. Jọṣua ọmọ-ogun Oluwa ati iranṣẹ Mose, kó awọn ọmọ-ogun lọ soju ija, Ẹksodu 17:9, 10; 24:13
3. Mose, pẹlu Aarọni ati Huri, awọn oluranlọwọ meji ti o fi ọkàn tán, gbe ohùn adura soke fun ẹgbẹ-ogun Israẹli, Ẹksodu 17:9, 10; 24:14
4. Adura Mose ati itilẹhin Aarọni pẹlu Huri fun ni ni ẹ̀kọ́ iyebiye nipa adura, Ẹksodu 17:9-12
5. A ṣẹgun Amaleki nitori ijolootọ́ awọn aṣiwaju ti Ọlorun yàn, Ẹksodu 17:12, 13
6. A paṣẹ fun Mose lati kọ akọsilẹ iwa arékerèkè awọn ara Amaleki, Ẹksodu 17:14; Deuteronomi 25:19; I Samuẹli 15:2, 3; II Samuẹli 1:1; I Kronika 4:42, 43
7. A ni ifihan Ọlorun miran nipasẹ orukọ mimọ yi, Jehofa-nissi, Ẹksodu 17:15, 16; 6:3; 15:26

## ALAYE

**Irahun Dipo Igbẹkẹle**

Ni oroowurọ ni awọn ọmọ Israẹli maa n fi agọ́ wọn silẹ ki oorùn to goke, won a si kó ounjẹ ọrun jọ eyi ti Ọlọrun ran si wọn lati fun ara wọn lokun. Wọn ṣẹṣẹ ni ipese aparo fun ẹran jijẹ ni ọna iyanu ni, nitori bẹẹ wọn ko i ti le gbagbe rara bi Ọlọrun ti ṣe pese fun aini wọn. Ni kikùn si Mose nigba ti wọn kò ni omi lati mu, wọn jẹ alai ronu, alai more, ati alai gbagbọ́.

Wọn jẹ alai ronu, nitori Mose kan jẹ iranṣẹ Ọlọrun ni, oun pẹlu si jẹ alabapin ninu ipọnju won. wọn jẹ alai moore, nitori Mose ti sa gbogbo ipa rẹ fun wọn lati ibẹrẹ -- **ki i** ṣe fun ère tabi fun ogo ti rẹ bi ko ṣe fun ire wọn. Wọn jẹ alai gbagbọ́, nitori o yẹ ki wọn mọ pe Mose yoo tun bẹbẹ fun aini wọn.

**N jẹ Ọlọrun ni O gba Israẹli La tabi Mose?**

Ṣugbọn ki a sọ tootọ, kikùn wọn ki i ṣe si Mose. Ọlọrun ti i ṣe Olugbala wọn kuro ni Egipti, ati Amọ̀na, Alaabo ati Olupese wọn lati igba naa titi di isinsinyi ni wọn kùn si. Mose ti wi fun awọn Ọmọ Israẹli pe Ọlọrun ni wọn n kùn si, bi wọn tilẹ doju kọ ẹlomiran. Aigbagbọ́ wà ninu kikùn wọn yi, o ti yọ̀ kẹ́lẹ́ wọ inu wọn; boya wọn ko tilẹ fura. Nigba ti wọn wi fun Mose pe, "Etiri ti iwọ fi mú wa goke lati Egipti wá"? wọn fi hàn pe wọn kò gbagbọ́ pe Ọlọrun ni o da wọn nide, wọn ṣe bi ọgbọ́n ati mimọ ọn ṣe alakoso wọn onirẹlẹ nikan ni. O yẹ ki wọn ti mọ pe igbala wọn jẹ lọna awamaridi, nipa ọwọ́ Ọlọrun nikan. Bi o ba ṣe pe ni idanu aṣiwaju orilẹ-ède wọn ni ilana yi ti wa, oun I ba ti ṣeto silẹ fun iru akoko pajawiri bayi.

**"Nipa Igbagbnọ́ li o kọ Egipti silẹ"**

Mose ti gbe inu aginju naa fun ogoji ọdun, dajudaju o si mọ ohun ti o wà niwaju wọn. O mọ̀ pe lai si iṣẹ-iyanu kò ni ṣe e ṣe lati bọ́ ọ̀pọ eniyan bi iru eyi ninu aginju naa. Ṣugbọn o mura tan lati tẹsiwaju gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun lai ka awọn iṣoro ti oun mọ̀ pe o wà niwaju wọn si, eyi ti o fi titobi igbagbọ́ rẹ̀ hàn. Abrahamu fi ilu ti a bi i silẹ o si jade lọ lai mọ ibi ti oun n rè, ṣugbọn Mose jade, o mọ̀ ohun ti o wà niwaju ati ohun ti awọn eniyan ti oun n kó lọ ni lati ni. Gbogbo nkan kò ṣee ma ni wọnyi kò si si nilẹ. O yẹ ki igbagbọ́ bi iru eyi ru itara awọn Ọmọ Israẹli soke lati gbẹkẹ le Ọlọrun Ẹni ti ko ja wọn tilẹ ri.

A ti ri sẹhin, a o tun maa ri nigba pupọ niwaju ẹkọ wa, orisun igbagbọ́, agbara, ati igboyà Mose: nigbakigba ti o ba ko iṣoro, oun a “kepe OLUWA.” A o si ri i pe Ọlọrun kò ja a tilẹ ri; nitori nigbakigba ti Mose ba bẹbẹ fun awọn ọmọ Israẹli, Ọlọrun a gbà wọn! Bakan naa ni ni akoko yi. Ọlọrun paṣẹ fun Mose, Mose si gbọran. O lọ pẹlu awọn agbaagba Israẹli sibi apata kan, o si fi ọpa rẹ lu u. Loju kan naa omi tú jade lati inu apata naa.

**Kristi Apata Wa**

Apata yi jẹ apẹẹrẹ nla nla ti Oluwa ati Olugbala wa. Jesu wá lati gba wa lọọ iku ti o daju, ṣugbọn a kò le ṣe alai ma kọ lu U ki iye ainipẹkun to le jẹ ti wa. Omi duro fun ounjẹ ti ẹmi ati awọn ibukun ti Ihinrere ti n tu ọkan lara. Nibi pupọ ninu Iwe Mimọ́, o jẹ apẹẹrẹ awọn ibukun ti igbala (Isaiah 55:1; Johannu 4:14). Ninu I Kọrinti 10:4, Apọsteli nì n sọ fun ni pe a fun Israẹli ti Majẹmu Laelae ni igbala kan naa ti a n ri gbà nitori “Kristi si li Apata na.”

Iwe itan sọ fun ni nipa ọna iyanu ti Ọlọrun gbà fi yọ awọn ti o ke pe E ninu ipọnju. Ninu Ogun Abẹle nigba ti ọpọ awọn ọmọ-ogun kan wà ninu àhámọ ologun ni Andersonfille, ni Georgia (ilu kan ni Amẹrika) Ọlọrun ṣe iṣẹ-iyanu kan ti o gba ẹmi ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan ti o wà ninu irora wọnyi là. Awọn ọmọ-ogun ti a kó lẹ́ru wọnyi n kú lọpọlọpọ nitori oungbẹ, ebi, aisan ati otutu. Ninu ipò yi ọpọ ninu wọn gbadura fun iranwọ, Ọlọrun si ran iji lile kan eyi ti o mu ki orisun omi kan bẹ̀rẹ si i ṣàn, o si wa titi di oni, oun ni a n pe ni Orisun Agbara Ọlọrun.

**Iwa Arékérekè Awọn Ara Amaleki**

Orilẹ-ede ekinni ti Israẹli ba pade ni awọn ara Amaleki (Numeri 24:20). Awọn eniyan wọnyi jẹ iran Amaleki, ọkan ninu awọn ijoye Elifasi, ọmọ Esau, arakunrin jakọbu, wọn si tipa bẹẹ tan mọ awọn Ọmọ Israẹli (Gẹnẹsisi 36:15, 16). Eniyan i ba rò pe o yẹ ki wọn ti ran awọn ọmọ Isaẹli lowọ dipo eyi ti wọn fi doju kọ wọn lọna ẹ̀wẹ́ ati ojo. Boya ifura ati ilara, pẹlu ibẹru ogunlọgọ iru eniyan bayi ninu aginju, ni o fa iwa wọn ti wọn si pinnu lati dena awọn ọmọ Israẹli lati kọja ni agbegbe wọn. Wọn kọ́kọ́ bẹrẹ lati dẹru ba wọn, lẹhin naa wọn kúkú doju ija kọ ẹgbẹ-ogun Israẹli ti a ṣẹṣẹ yan. Ṣugbọn Amaleki ki o ti mọ orisun agbara Israẹli, bẹẹ ni ko si ti i mọ pe lati doju ija kọ awọn ayanfẹ Ọlorun, iṣubu ti o daju ni yoo yọri si.

**Jọṣua, Iranṣẹ Mose**

Nihin yi, ni akoko idaamu, a fi ẹni titun miran hàn. Dajudaju, Jọṣua ki i ṣe ajeji si awọn Ọmọ Israẹli; nitori a sọ pe o di ipo pataki kan mu lẹgbẹ aṣaaju wọn, Mose. Ati gẹgẹ bi ède ti a lo ninu ẹkọ a, a ri i pe Ọlọrun ti doju sọ ọ gẹgẹ bi ẹni ti yoo gba ipo Mose lẹhin ọla. Nisinsinyi a fun un laṣẹ lati yan ẹgbẹ ọmọ-ogun ki o si ba awọn ara Amaleki ja. A mọ̀ nipa ohun gbogbo ti o ṣẹlẹ ni aginju pe ọkunrin ti o ni igbagbọ́ ni oun i ṣe. O ni lati jẹ ẹni ti o le mu ki awọn ẹlomiran ni ẹmi igboya ati ijolootọ́.

Awọn ẹlomiran tọka si Jọṣua gẹgẹ bi apẹẹrẹ Jesu ti o han gbangba nitori ti Jọṣua ba awọn ọta awọn eniyan ti o mu wọ Ilẹ Ileri jà, o si ṣẹgun wọn. Itumọ orukọ rẹ ni **Olugbala kan**, a si tumọ rẹ ninu Majẹmu Titun (ti ede Oyinbo) si **“Jesu”** (Iṣe Awọn Apọsteli 7:45).

Iṣẹgun jẹ ti Israẹli nitori igboya Jọṣua, pẹlu itilẹhin adura ẹbẹ Mose. Mose lọ si ori oke pẹlu ọkunrin olootọ meji, Aarọni ati Huri, nibẹ ni o si gbe ọpa Ọlọrun soke Ọrun ninu adura. Niwọn igba ti o ba n gbadura awọn ọmọ Israẹli a bori, ṣugbọn nigba ti ọwọ ba kún un ti o si wálẹ̀ nitori aarẹ ara, awọn Amaleki a bori. O dara lati ni igboya nigba iṣoro ati idanwo, ṣugbọn igboya nikan kò tó. Ni iru akoko bawọnyi a n fẹ iranwọ Agbara kan ti o ju ti wa lọ, nipa adura ni eyi si le ṣe e ṣe.

**Ifarahàn Ọlọrun lọna ti O ju ti Atẹhinwa**

“Ọpa Ọlọrun” (Ẹksodu 17:9) ni ohun-elo ti a le foju ri ti a lo lati fun Israẹli ni iranwọ ati igboya lakoko yi. Èdè Heberu ti a tumọ̀ si **Ọlọrun** nihin jẹ orukọ ti o duro fun agbara iṣẹda Ọlọrun, ipá Rẹ̀ ati bibori Rẹ̀ lori ohun gbogbo -- **akopọ** orukọ Ọlọrun. Paapaa, a n lo o nigba ti a ba n sọ ti ibalo Rẹ̀ pẹlu awọn orilẹ-ède, yatọ si **Jehofa (OLUWA)** eyi ti a lò lati sọ nipa ibalo Rẹ̀ pẹlu Israẹli. A ti ri i pe o ni idi pataki ti Ẹmi Mimọ́ fi yan awọn orukọ wọnyi, itumọ wọn si jinlẹ nipa ti ẹmi.

Nibi ti igbẹ ti n jo Ọlọrun fi ara Rẹ̀ hàn fun Mose gẹgẹ bi **Jehofa;** nibi Okun Pupa, gẹgẹ bi **Jehofa, agbara mi;** ati ni Mara, gẹgẹ bi **Jehofa munilarada**. Nisinsinyi ni Refidimu Ọlọrun tun fi apa miran hàn nipa iwa Rẹ̀ ati titobi Rẹ̀. nigba ti wọn ṣẹgun, Mose tẹ pẹpẹ kan, nibẹ ni Ọlọrun si fara hàn gẹgẹ bi Jehofa-nissi ti a tumọ si **OLUWA Ọpagun mi.** Oun ni Balogun ti a n tẹle ati Olori ẹgbẹ-ogun ninu eyi a gbe wa.

Nigba ti a ba ré idanwo ati iṣoro kan kọja a maa n ni oye titun ti o si jinlẹ nipa bi Ọlọrun ti jẹ si wa, ati ohun ti O le ṣe fun ni. Iṣoro kọọkan maa n mu ni sun mọ Ọlọrun si i, bi a ba tọ Ọlọrun lọ ni akoko idaamu naa ni ọna ti o yẹ. Nigbakuugba ti a ba ni ifarahan si i nipa Ọlọrun ti a fẹran, o yẹ ki a tubọ ni igbọran atinuwa si I. Igbọran kọọkan ni o si n fi èrè kun un fun wa ninu ayeraye. Bayi ni a ri i pe awọn ti o n mọ Ọlọrun ju lọ ni awọn ti a ti ti ọwọ́ Rẹ̀ da silẹ ni igba pupọ ni akoko idanwo; bi wọn si ti n moye Rẹ̀ pupọ si i, o yẹ ki wọn fi bẹẹ sin In pẹlu.

**AWỌN IBEERE**

1. Kin ni a n pe agbegbe ibi ti awọn Ọmọ Israẹli pagọ si ni akoko yi?
2. Kin ni aini wọn nipa ti ara nihin?

3. Kin ni iha ti wọn kọ si aini wọn yi?
4. Kin ni ẹọ ti a le ri kọ́ ninu iwa awọn Ọmọ Israẹli nihin, nipa awọn ojiṣẹ Ọlorun ati awọn alakoso wa?
5. Kin ni Mose ṣe ti o wú ni lori to bẹẹ?
6. Kin ni ṣe ti Mose sọ ibudo wọn ni Massa ati Meriba?
7. Ọna wo ni awọn ara Amaleki fi gba bá awọn Ọmọ Israẹli tan?
8. N jẹ a le maa reti nigba gbogbo pe awọn ibatan wa yoo wa ni iṣọkan pẹlu wa ninu awọn ohun ti i ṣe ti Ọlọrun?
9. Kin ni ipa ti Aarọni pẹlu Huri sà ninu ogun ti wọn ba awọn ara Amaleki ja?
10. Ifarahan nla nipa Ọlorun tikara Rẹ̀ wo ni Ọlọrun fun wọn lakoko yi?